# OUNJẸ ALẸ IKẸYIN ATI GẸTSEMANE

**Matteu 26:17-46; Johannu 13:1-17; 1 Kọrinti 11:23-30**

**ẸkỌ 62 – FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Lõtọ o ti ru ibinujẹ wa, o si gbe ikãnu wa lọ" (Isaiah 53:4).**

## Ajọ Irekọja

Ọjọ kin-in-ni igba ajọ aiwukara ni Ajọ Irekọja, ọjọ ti awọn Ju maa n ṣe ajọyọ iranti idasilẹ awọn baba nla wọn kuro ninu oko-ẹru ni Egipti ni iwọn ẹẹdẹgbẹjọ (1,500) ọdun sẹyin. A ranti pe wọn ti pa ọdọ-agutan naa wọn si ti fi ẹjẹ rẹ si opo ẹnu-ọna wọn lati gba akọbi wọn lọwọ ikú ni alẹ ọjọ naa ti angẹli apanirun la Egipti kọja. Ọdọ-agutan yii ni a n pè ni ọdọ-agutan irekọja, o si jẹ apẹẹrẹ Jesu Ẹni ti yoo wá ti yoo si ta Ẹjẹ Rẹ silẹ fun irapada. Ni alẹ ọjọ kan naa ti a pa agutan naa, ni awọn Ọmọ Israẹli bẹrẹ irin-ajo wọn si Ilẹ-Ileri. Lati igba yii wá fun ọpọlọpọ ọdun ni awọn Ọmọ Israẹli ti n ṣe eto irubọ yii; ṣugbọn lati igba yii lọ kò tun ni ṣe anfaani mọ́ nitori nisisiyii Ọdọ-Agutan irekọja tootọ, Jesu tikara Rẹ ni lati kú fun wa. "Nitori a ti fi irekọja wa, ani Kristi, rubọ fun wa" (1 Kọrinti 5:7). Lẹyin ti o ti ta Ẹjẹ Rẹ silẹ, kò tun si anfaani kan ninu tita ẹjẹ ọdọ-agutan silẹ lati ọdun dé ọdun mọ́.

Jesu maa n kiyesara pupọ lati pa gbogbo ofin ati ilana isin ti Ọlọrun palaṣẹ fun awọn eniyan Rẹ ti O yàn mọ́; nitori naa a rí i pe nisisiyii O bẹrẹ si i mura silẹ fun Ajọ Irekọja. Awọn imurasilẹ miiran wà yatọ si ti ọdọ-agutan. A ṣe akiyesi pe eyi ni ọjọ kin-in-ni ajọ aiwukara. Itumọ eyi ni pe ni akoko yii ki yoo si iwukara rara ninu akara wọn eyi ti o lè mú ki ó wú, ṣugbọn yoo tẹ́ pẹlẹbẹ bi akara pẹlẹbẹ-pẹlẹbẹ.

## Iwukara

Iwukara jẹ́ apẹẹrẹ ẹ̀ṣẹ nitori o dabi ohun ti o ti wú tabi ti o bajẹ, a si maa pọ si i tabi ki o maa wú soke kiakia. Jesu pe e bẹẹ nigba ti O wi pe "Ki ẹ si mã ṣọra niti iwukara awọn Farisi ati ti awọn Sadusi" (Matteu 16:6). Nitori eyi awọn Ju ki i fi iwukara sinu akara wọn laaarin awọn ọjọ mimọ́ yii, wọn a si ṣọra lati ri i pe kò si ninu ile wọn pẹlu. Gbogbo kọrọ ni wọn o gbá finnifinni; wọn a si yi inu apo wọn sode lati le mọ dajudaju pe kò si ọ̀kan ti o fara pamọ sibẹ; awo ọtọ patapata ti a fi n bu ounjẹ ni wọn n lò ni akoko yii, eyi ti wọn mọ daju pe kò le ni iwukara ninu. (Awọn Farisi naa n ṣe ọfin-toto pupọ nipa awọn eto ode-ara yii, ṣugbọn wọn kò bikita rara nipa ẹ̀ṣẹ ti o wà ninu ọkàn wọn).

Igba Ajọ Irekọja yii maa n jẹ igba ayọ̀ nitori o jẹ igba iranti iṣẹgun lori awọn ọta wọn; ṣugbọn alẹ yii jẹ alẹ ibanujẹ nitori Jesu ti kilọ bayii "Akokò mi sunmọ etile." Bi wọn ti n jẹun O sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ mejila pe ọ̀kan ninu wọn yoo fi Oun hàn. Eyi mu idaamu nla ba awọn mọkanla ti ara wọn mọ́; ẹni kan ninu awọn mejila yii ti o ti ni ibalo timọtimọ bẹẹ pẹlu Olugbala ha le ṣe iru nnkan bẹẹ bi? Wọn ti mọ ifẹ ati ẹmi ibakẹdun Rẹ, wọn si ti ri iwa iṣeun ati aanu Rẹ. Awọn alaisan ti ri iwosan, O ti jí oku dide, O si ti sọ awọn ẹlẹṣẹ di ominira. Jesu si n sọ nisisiyii pe ọ̀kan ninu wọn yoo fi Oun hàn -- ẹni kan ti ta A fun ọgbọ̀n owó fadaka.

## Tita Olugbala

A n dá Judasi lẹbi pe onikupani eniyan ati ojo ni. Ṣugbọn nitori ohun ti ko ni laari to eyi paapaa ni awọn eniyan ṣe maa n sẹ́ Jesu lọjọ oni. Boya ọdọ kan yoo pada sẹyin kuro lọdọ Oluwa nitori awọn ẹlẹgbẹ rẹ̀ n fi ṣe yẹyẹ́. O n ta Olugbala rẹ fun ohun ti kò ni laari ni. Aṣa ayé yii le mu ki ẹlomiran kọ Jesu silẹ. Wò o bi o ti ta Oluwa rẹ̀ ni ọ̀pọ! Ko si ẹni kan laaarin wa ti o lagbara ṣugbọn pe ki a maa ṣọra ki a si maa gbadura ki a ma ba dán wa wò lati da Ọlọrun wa.

## Ounjẹ Alẹ Oluwa

Lẹyin ti wọn ṣe Ajọ Irekọja tan, Jesu fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ni ilana miiran lati maa pamọ -- Ounjẹ Alẹ Oluwa. Gẹgẹ bi awọn Ju ṣe ni lati pa Ajọ Irekọja mọ pẹlu ifoju sọna fun bibọ Kristi ni akọkọ, bakan naa ni awọn Onigbagbọ́ ni lati maa foju sọna fun bibọ Jesu lẹẹkeji nigba ti wọn ba n ṣe alabapin ninu ilana isin yii. A ni lati maa ranti iku Rẹ̀ "titi yio fi de" (1 Kọrinti 11:26).

Paulu fun wa ni awọn itọsọna kan nipa Ounjẹ Alẹ Oluwa, o sọ fun wa pe ẹni kọọkan wa ni lati wadii ara rẹ̀ wo, ipo ti o wà nipa ti ẹmi, ki o si ri i pe oun yẹ lati jẹ ninu apẹẹrẹ tabili Oluwa. Nigba ti Jesu bu akara naa ti O si fi i fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀, O wi pe " Eyiyi li ara mi," nigba ti O si fi ago naa fun wọn o ni "Eyi li ẹ̀jẹ mi." Ara Rẹ̀ yoo kú a oo si ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ fun imukuro ẹ̀ṣẹ wa ki alẹ ọjọ miiran to lẹ́; ni ibi ase-alẹ yii, Oun n fi ara Rẹ̀ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ni apẹẹrẹ. Nigba ti a ba wá si ibi ounjẹ Alẹ Oluwa a ni lati ranti pe akara ti a n jẹ jẹ́ apẹẹrẹ ara Kristi ti a fà ya, bẹẹ ni oje eso-ajara ti a n mu jẹ apẹẹrẹ Ẹjẹ Rẹ̀. Njẹ a le ṣe alabapin ninu awọn apẹẹrẹ mimọ́ yii pẹlu ẹ̀ṣẹ ninu ọkàn wa bi? "Ẹnikẹni ti o ba njẹ, ti o ba si nmu laimọ̀ ara Oluwa yatọ, o njẹ o si nmu ẹbi fun ara rẹ̀" (1 Kọrinti 11:29). A ni lati wá ni irẹlẹ si iwaju Kristi ki a si ni ki O fi Ẹjẹ Rẹ̀ bò wa lọtun, nitori boya a ti le ni ero buburu kan lọkan si arakunrin wa, tabi boya a ti kuna ninu iṣẹ wa si Ọlọrun, tabi a ti kùn nitori ipin wa ni ayé. A ni lati sọ ẹ̀jẹ́ wa ati ifi-ara-rubọ wa di ọtun, bi ede-aiyede ba si wà laaarin awa ati ẹni keji wa, a ni lati mu eyi tọ́ ki a to jẹ ounjẹ Alẹ Oluwa.

Bi a ba wá ni iru ipo bayii, pẹlu igbagbọ́ ninu Jesu, a oo ri ikiya nipa ti ẹmi gba lọwọ Ọlọrun, agbara ọtun lati ṣiṣẹ, iwosan fun ara wa bi a n ṣaisan; a oo si gbadun irẹpọ pipé pẹlu awọn eniyan Ọlọrun. A oo gbadun idapọ mimọ́ iru eyi ti a ko le ri ninu aye. Ọrun yoo súnmọ wa, ọkàn wa yoo si maa ṣiṣẹ bi ago ni ireti pe Jesu yoo farahàn lati wá mu awọn ayanfẹ Rẹ̀ lọ si ibi Ase Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan. Ẹ maa ṣe eyi "titi yio fi de."

**Wiwẹ Ẹsẹ̀**

Ọpọ ayọ ni o kù sibẹ fun Onigbagbọ́ ti o n pa gbogbo Ofin Ọlọrun mọ. Lẹyin ounjẹ-alẹ wọn, Jesu fi gele kan di ara Rẹ̀ ni amure O si bẹrẹ si i wẹ ẹsẹ̀ awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀. Nigba ti O ṣetan O ni, "Njẹ bi emi ti iṣe Oluwa ati Olukọni nyin ba wẹ̀ ẹsẹ nyin; o tọ́ ki ẹnyin pẹlu si mã wẹ̀ ẹsẹ ara nyin. . . . . Bi ẹnyin ba mọ̀ nkan wọnyi, alabukun-fun ni nyin, bi ẹnyin ba nṣe wọn" (Johannu 13:14-17). Jesu tun wi pe, "Bi ẹnyin ba fẹran mi, ẹ ó pa ofin mi mọ́" (Johannu 14:15), dajudaju aṣẹ si ni eyi. Ọpọlọpọ ni awọn ẹlẹsin lode oni ti kò gba ilana yii si ohun ti o ṣe pataki, ṣugbọn aṣẹ Ọlọrun ni, "alabukun-fun ni nyin, bi ẹnyin ba nṣe wọn." Awọn miiran maa n ṣe awawi pe aṣa wọn ni igba laelae ni wiwẹ ẹsẹ̀ jẹ́ nitori awọn eniyan naa n wọ salubata ti ko bo ẹsẹ̀, bẹẹ ni ọna si jẹ́ ọna ekuru, ṣugbọn bi o ba jẹ bẹẹ, iru iwẹsẹ bẹẹ ni o yẹ ki wọn ti ṣe nigba ti wọn ba ṣẹṣẹ wọle ki yoo si jẹ lẹyin ti wọn ti pari ounjẹ-alẹ tán.

**Kò ni Ipin Lọdọ Jesu**

Peteru kò ka ara rẹ yẹ ni ẹni ti Oluwa rẹ le wẹ ẹsẹ rẹ; ṣugbọn nigba ti o gbọ ọrọ wọnyii, "Bi emi kò ba wẹ̀ ọ, iwọ kò ni ìpin lọdọ mi," o yara dahun, "Oluwa ki iṣe ẹsẹ mi nikan, ṣugbọn ati ọwọ́ ati ori mi pẹlu" Peteru rò pe gbogbo ayé oun ni oun ti fun Ọlọrun; o ni itara ati aayan fun Kristi, ṣugbọn kò mọ ailera rẹ̀. Ni alẹ yii gan an ni oun yoo sẹ́ Oluwa rẹ̀! "Nitorina ẹniti o ba rò pe on duro, ki o kiyesara, ki o má ba ṣubu" (1 Kọrinti 10:12). Peteru fi igboya wi pe bi gbogbo awọn ọmọ-ẹyin iyoku tilẹ kọ Jesu silẹ, oun yoo jẹ́ oloootọ. Ki ni ṣe, o ti mura tán lati kú fun Kristi! Dajudaju ohun ti o pinnu ninu ọkàn rẹ̀ ni o sọ, ṣugbọn oun ko ṣọra ko si gbadura bẹẹ ni idanwo si bori rẹ. Jesu kilọ fun Peteru pe ki ilẹ to mọ́, ki i ṣe kiki pe yoo ti sẹ́ Oluwa rẹ̀ lẹẹkan nikan, ṣugbọn ni igba mẹta.

**Wọn Sùn**

Lẹyin idapọ didun ti wọn ti ni, Jesu mu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ lọ si Ọgbà Gẹtsemane lati gbadura. O ni ki awọn mẹjọ duro ni ibi kan, O si mu Peteru, Jakọbu ati Johannu awọn ẹni ti o súnmọ Jesu julọ, lọ siwaju si i ninu ọgbà. O ti sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe ni alẹ ọjọ naa ni wọn o lu Oluṣọ-agutan awọn naa yoo si tuka bi agutan; O si ti fi hàn ninu ọrọ Rẹ̀ pe Oun o kú ni iwọn bi o ti sọ fun wọn pe Oun o pade wọn ni Galili lẹyin ti Oun ba jinde ninu oku ṣugbọn o dabi ẹni pe ohun ti O n sọ kò yé wọn rara.

Peteru, Jakọbu ati Johannu ti gbadun iru ifaramọra ti o pọ̀ bẹẹ pẹlu Kristi iru eyi ti ẹlomiran kò mọ̀. Wọn ti wà pẹlu Rẹ̀ lori oke Ipalarada, wọn si ti ri I nigba ti a ṣe E logo niwaju wọn. Nisisiyii olufihan ni n sunmọ tosi, Jesu si ni ki wọn ba Oun ṣọna. Njẹ wọn ṣe bẹẹ? O lọ si iwaju diẹ kuro lọdọ wọn lati gbadura -- awọn si sùn! Awọn ti wọn ti sọ pe awọn ó ba Jesu kú, paapaa Peteru, wọn sùn nigba ti Oluwa wọn wà ninu ewu to la ikú lọ! Ronu ijakadi ti ẹmi ati ti ero ti Jesu là já ni alẹ ọjọ ni – o si dabi ẹni pe awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ kò moye irora Rẹ̀.

**Irora Inu Ọgbà**

Ninu ọgbà ni iṣẹlẹ ijakadi nla ti Jesu jà ti ṣẹlẹ; nihin Iwa-Ọlọrun ti o wà ninu Rẹ̀ eyi ti o ti Ọrun wá lati san igbese irapada n jijakadi pẹlu ara eniyan ti O gbé wọ̀ ti o n fẹ fa sẹyin kuro ninu ijiya naa. Ọlọrun ti rán ọmọ Rẹ̀ ni awọ eniyan lati ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ ki a ba le gba wa la; ninu imuṣẹ iṣẹ-iranṣẹ Rẹ̀ nihin O jiya gẹgẹ bi eniyan ki O ba le mọ bi yoo ṣe le fara da fun wa ninu iyà wa. Ṣugbọn ni alẹ ọjọ yii O jiya pupọ fun wa. Wò o bi inu wa ti n bajẹ to nigba ti a ba dá ẹ̀ṣẹ kan ṣoṣo! Bẹẹ gẹgẹ ni Jesu ni ibinujẹ fun ẹ̀ṣẹ gbogbo agbaye. O yẹ fun wa lati jiya fun ẹ̀ṣẹ wa, ṣugbọn Jesu san gbese wa O si jiya ni ipò wa.

Nigba ti Kristi woye bi iwuwo ẹ̀ṣẹ aye ti pọ to, O wolẹ silẹ, O si kigbe si Baba, "Jẹ ki ago yi ki o kọja kuro lori mi," ṣugbọn O tun yara fi kun un pe "kì má ṣe bi emi ti nfẹ, bikoṣe bi iwọ ti fẹ." O ni lati mu aago naa. O ni lati jiya ikú lori agbelebu, lati mu eto irapada ṣẹ. Ni oru ọjọ yii O jọwọ ifẹ Rẹ̀ patapata fun Ọlọrun; nihin ni O ṣẹgun ẹrù nla ti agbelebu eyi ti O mọ pe O wà niwaju Oun. Nigba ti O pari adura Rẹ̀ tán O le lọ ni igboya lati pade olufihan ni. O ti ṣẹgun iboji nibi ti yoo lọ lai pẹ, ṣugbọn Oun nikan ni O gbadura!

**Ẹ Maa Ṣọna, Ki Ẹ Si Maa Gbadura**

Awọn ọmọ-ẹyin ti wọn ti n leri to bẹẹ ni wakati diẹ sẹyin -- wọn ro pe gbogbo wọn ni o ṣe tan lati kú fun Un -- ti sùn lọ! Lẹyin ti Jesu gbadura lẹẹkinni ti O wá ti O si ba wọn ti wọn n sùn, O wi pe: "Ẹnyin ko le bá mi ṣ̀ọna ni wakati kan?" Eyi ni ha pọ ju bi? O kilọ fun wọn pe ki wọn ki o maa ṣọna ki wọn si maa gbadura, ki i ṣe nitori ti Rẹ̀ nikan, ṣugbọn ki awọn ma baa bọ́ sinu idanwo. Njẹ o ro pe bi wọn ba ti ṣọra ki wọn si gbadura pẹlu Jesu, ki wọn si ran An lọwọ pẹlu igbagbọ́ wọn lati ru ẹrù naa wọn i ba ti ni agbara lati bori idanwo ti o de ba wọn lai pẹ lẹyin eyi? Njẹ iwọ ha ri i bi o ti ṣe pataki to lati ṣọna ati lati maa gbadura? A n fẹ lati ṣe bẹẹ ṣugbọn ohun ti o pọ ju fifẹ lasan ni lati wulo ninu iṣẹ Ọlọrun. A ni lati ṣe aapọn. "Lõtọ li ẹmi nfẹ ṣugbọn o ṣe alailera fun ara."

Awọn ọmọ-ẹyin sùn nigba ti ọta n sunmọ tosi. Ki ni wọn n ṣe lonii? Ẹru ba wa pe ọpọlọpọ ti o n wi pe awọn jẹ ọmọ-ẹyin Jesu ni o wà ninu oorun ti ẹmi nigba ti ẹ̀ṣẹ n gbilẹ si i, ti o si mú ọpọlọpọ lọ sinu ọgbun òkunkun gẹgẹ bi ọjọ egbe ti n sunmọ etile. Ọna kan ṣoṣo lati ri agbara gbà lati bá eṣu jà ni nipa adura, adura agbayọri. Njẹ awa ko ha le ba Jesu ṣona ki a si ba A gbadura fun "wakati kan?"

> **"Wo o! iwọ ti n mi kanlẹ ti o si poungbẹ, Ti o n ṣọfọ fun agbara,**
> **Gbọran si ọrọ kẹlẹkẹlẹ yii, 'Iwọ ko ha le ṣọna fun wakati kan?'**
> **Kò si 'ọna gbẹ̀fẹ́' kan lati so eso, Ati lati ri ibukun gba;**
> **Ọna si agbara lati ṣiṣẹ mimọ́, Ni nipa gbigba adura."**

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni Ajọ Irekọja? Bawo ni Jesu ṣe mu un ṣẹ?
2. Nibo ni Jesu sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ pe ki wọn mura silẹ fun Un?
3. Awọn wo ni o ba A jẹ Irekọja?
4. Taa ni fi Jesu hàn? Fun eelo ni?
5. Njẹ o tọna fun wa lati pa ilana iwẹsẹ mọ́? Ki ni ṣe?
6. Njẹ awọn ọmọ-ẹyin Jesu ha jẹ iranlọwọ fun Un ninu ọgbà? Ki ni wọn ṣe?